IROHIN PATAKI FUN ỌDUN KERESIMESI

# Irohin Yoruba

No. 759 DECEMBER 23 — DECEMBER 29, 1959 Kobo Meji (2D.)

**OWE**

ANJUWỌN ko ṣe wi lejọ ija ilara ko tan boro.
Agbalagba ti yio te ile tutu yio da omi siwaju.
Igba ki i tọ lọ bi orere aiye ki i lọ bi opa ibọn.

**LAKAYE ỌRỌ**

OJU Oluwa mbẹ lara awọn olododo, eti Rẹ si ṣi si igbe wọn.
Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu lati ke iranti wọn kuro lori ilẹ.
Awọn olododo nke. Oluwa si gbọ, o si yọ wọn jade kuro ninu iṣe wọn gbogbo.

# BALEWA YAN AWỌN MINISTA

NI ọsan ọjọ Aiku ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria yan awọn Minista merindinlogun fun Apapọ Ijọba titun Naijiria, awọn mẹsan lati inu Ẹgbẹ Olomi (NPC) ati awọn meje lati inu Ẹgbẹ Alakuko (NCNC).

Awọn Minista na ni:—

1. Alhadji Muhammadu Ribadu (NPC) Minista Alamojuto Eto Ilu Eko ati ti Ilẹ.
2. Oloye Festus Okotie-Eboh (NCNC) Minista Alamojuto Eto Inawo.
3. Ogbeni R. A. Njoku (NCNC) Minista Alamojuto Eto Iṣẹ Oko-ofurufu.
4. Alhadji Inua Wada (NPC) Minista Alamojuto Eto Iṣẹ ati Ile-Wiwọn.
5. Zanna Bukar Dipcharima (NPC) Minista Alamojuto Eto Iṣe-owo ati Iṣe-owo.
6. Ogbeni J. M. Johnson (NCNC) Minista Alamojuto Eto Iṣẹ ati Alafia Ilu.
7. Ogbeni Aja Nwachuku (NCNC) Minista Alamojuto Eto Eko.
8. Malam Maitama Sule (NPC) Minista Alamojuto Eto Isun-Ilẹ ati Agbara.
9. Malam Shehu Shagari (NPC) Minista Alamojuto Eto Ilosiwaju Iṣẹ Owo ati Iwadi.
10. Ogbeni Olu Akinfosile (NCNC) Minista Alamojuto Eto Iṣẹ Waya.
11. Malam Usman Sariki (NPC) Minista Alamojuto Eto Ọran Arin Ilu.
12. Ogbeni T. O. S. Benson (NCNC) Minista Alamojuto Eto Irohin Ijọba.
13. Alhadji Waziri Ibrahim (NPC) Minista Alamojuto Eto Ilera.
14. Malam Musa Yar Adua (NPC) Minista Alamojuto Eto Owo-Ifehinti, Idasile Iṣẹ ati Siso Ohunkohun di ti Ibile Naijiria.
15. Ogbeni M. T. Mbu (NCNC) Minista Asoju Ijọba Apapọ Naijiria.
16. Ogbeni M. A. Olanrewaju (NPC) Minista Asoju Ijọba Apapọ Naijiria.

**AWỌN AKỌWE MINISTA**

Awọn akọwe irifu Igbimọ ti Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria si tun yan ni:—

1. Ogbeni J. C. Ọbande, fun Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria.
2. Malam Hashim Adiya fun Minista Alamojuto Eto Alafia Eko.
3. Oloye H. Omo-Osagie, fun Minista Alamojuto Eto Inawo.
4. Oloye O. Oweh fun Minista Alamojuto Eto Iṣẹ.
5. Ogbeni D. C. Nguru, fun Minista Alamojuto Eto Eko.
6. Ogbeni F. E. Offor, fun Minista Alamojuto Eto Igbokegbodo Oko ati ti ọkọ-ofurufu.
7. Ogbeni M. Amechi, fun Minista Alamojuto Eto Irohin Ijọba.
8. Ogbeni C. O. Chiedozie fun Minista Alamojuto Eto Iṣẹ Waya.

Laipẹ ni Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria na yio sọ oruko awọn ti o ba tun fi kun un.

## Rotimi Williams di Agbẹjọro Ẹgbẹ Afẹnifẹre

NI ọjọ Iku ti iṣe ọjọ kerindinlogun oṣu yi ni awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ṣe ipade nla kan ni Ikenne, nibẹ ni nwọn ti yan Oloye Rotimi Williams ti o ti fi igbakan wa laye Minista Alamojuto Eto Idajọ Ododo ati Iṣẹ-ilu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun si ṣe Agbẹjọro Ẹgbẹ Afẹnifẹre. Nwọn si ṣe ikede rẹ ni ọjọ keji ni Ibadan.

Ni ibi ipade na ni nwọn ti ṣe ipinnu lati tun iṣe awọn agbẹjọro ẹgbẹ wọn (Ẹgbẹ Afẹnifẹre) ṣe dada fun awọn alatilẹhin wọn yika Naijiria. Nwọn ni iṣe ni Ipinlẹ Ariwa ni awọn yio ṣe atunṣe rẹ pupọ. Awọn

Wo oju ewe kerindinlogun

# KERESIMESI ỌDUN DE!



Baba Keresimesi npin ẹbun Ọjọ'ibi Kristi fun awọn ọmọde



# Oku ọlọmọ, gẹgẹ la o gbee

IWARO, OKA-OWO

### Adajọ sọ ẹniti o ji bata sẹwọn oṣu mẹta

IKARO

### Akọwe gba fun awọn ti o fi ẹgbẹ silẹ

IBADAN








# AWỌN AMOYE MẸTA WA FORIBALẸ F'ỌMỌ TITUN NA

Aworan isalẹ yi ni ti awọn amoye mẹta ti nwọn ti ila-orun wa si Jerusalẹm ti nwọn tọ pasẹ irawọ Jesu (Ọmọ titun) na wa si ibujẹ ẹran ti Maria bi i si ni Bẹtlẹhẹmu ti Judea. Nwọn raa lọrọ, nwọn kunlẹ nwọn si foribalẹ fun Jesu Ọmọ titun na.



Olorun pẹlu si ti gbe e ga gidigidi, o si ti fi orukọ kan fun un ti o bori gbogbo orukọ: "Pe ni orukọ Jesu ni ki gbogbo ẽkun maa kunlẹ, awọn ẹniti mbẹ ni ọrun ati awọn ẹniti mbẹ ni ilẹ ati awọn ẹniti mbẹ ni isalẹ ilẹ (Philip 2: 9 - 10)

## KERESIMESI

## KERESIMESI



# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

Lati Ọwọ E. Alabi Thompson


M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)
ARADAN STORES P.O.Box 2
EBUTE-METTA.





**OPE ni fun Ọlọrun Ẹlẹda wa fun Odun Keresimesi ti odun yi ti o ba wa ni ayọ ati alafia, Oluwa yio jẹki a fi ayọ se Odun na. Amin.**

Iranti Ọjọ-ibi Jesu Kristi ti a nṣe lọdọdun yi ti a npe ni Keresimesi, o yẹ ki gbogbo enia mọ itumọ ati ipilẹṣẹ odun na. Ẹni na ti a npe ni Jesu Kristi, ti orukọ Rẹ gbilẹ to bayi, Ẹni na ti Ọlọrun gbe ga ju gbogbo ẹda aiyeati ti ọrun lọ, Ẹni na ti Ọlọrun fi agbara ti o bori gbogbo agbara fun lori ohun gbogbo laiye ati l'orun, Ẹni na ni a nṣe ọdun Ọjọ'bi Rẹ lakoko yi, sibẹ ọpọlọpọ awọn enia lo wa laiye yi ti nwọn ko mọ nipa Ẹni nla na, tobẹ ti nwọn ma mbere bayi pe "Tani Jesu Kristi na?"

## BIBELI MIMỌ T'ỌRUN ỌWỌN IṢURA T'EMI

# "TANI JESU KRISTI NA?"

Iti gbogbo araiye ba mọ ẹniti Jesu Kristi iṣe, ti nwọn ba si mọ ododo ati ijinlẹ iṣẹ ati ọrọ ati Ẹkọ Jesu Kristi, dajudaju aiye iba dara ju bayi lọ, igbesi aiye enia iba si dun ju bayi lọ, ọpọ enia iba si jẹ onigbagbọ ododo ati enia rere ju bi gbogbo rẹ ti ri lode oni yi lọ. Awọn ẹlomiran a ma a fi ọrọ Jesu ṣe yẹyẹ nwọn a si ma a kẹgan Rẹ nitoriti nwọn ko mọ ẹniti Jesu Kristi iṣe. Otitọ ni owe ti awọn baba wa ma a npa bayi pe "Ẹniti ko mọ ni lo nfi ni ṣire". Bi ọba ilu Oyinbo ba bọ gbogbo ọla ati ogo rẹ silẹ ti o ba wa si ilẹ wa, bi a ko ba mọ ọ a le pe e ni "Koran" kan lasan, a sile fi orisirisi ẹgbin lọ ọ gẹgẹ bi ojiya Oyinbo kan lasan, nitoriti a ko mọ o pe ọba kan pataki ni iṣe.

Awọn ti ko mọ ẹniti Jesu Kristi iṣe, awọn ni ko gba A gbọ, awọn ti nwọn ko mọ ọ, awọn ni nwọn nkẹgan Rẹ, ti nwọn si nfi orukọ Rẹ ṣe yẹyẹ, nitorina ni a fi sọ nipa ti Jesu Kristi na ninu John ori 1 ẹsẹ 10, bayi pe, "On si wa li aiye, aiye ko si li a si ti da aiye, aiye ko si mọ ọ". Titi di oni yi, awọn ti ko mọ Jesu Kristi pọ laiye nitorina ni awa Iranṣẹ Oluwa gẹgẹ bi Aposteli, Woli Evangelist, Pastọ, Katikist, Alufa-Ijọ ati gbogbo awọn ti o ku dide lati mura gidigdi lati fi Kristi han araiye, ki a maṣe tiju, tabi bẹru lati sọ otitọ nipa Jesu fun araiye, nitoripe Ẹni na ti a nwi yi, o fẹrẹ de.

Gbogbo wa gẹgẹ bi onigbagbọ ni gbogbo Ijọ ati ni gbogbo aiye, ẹ yago pelu iyapa ati ikẹgan ara wa, ẹ jẹki a fi imọ ṣọkan lati gba orukọ Jesu ga, ki awọn ti o wa ninu okunkun le ri imọlẹ, ki awọn ti eṣu ntan-

Lati ọwọ Evangelist Akande, Ogbomọṣọ

jẹ le mọ otitọ, ki nwọn si le bọ si oju ọna igbala, ki gbogbo awa enia Ọlọrun le jogun iye ainipẹkun lọjọ ikẹhin.

Gẹgẹ bi akoko yi ti jẹ akoko ayọ fun iranti odun ọjọ-ibi Jesu Kristi Olugbala wa, awa onigbagbọ ni ọmọ ọlọdun, bi a o ti ma a jẹ, ti a o si ma a mu, ẹ jẹki a yago fun ijẹkujẹ ati oti amupara, ki a si yago fun iwakiwa ti o ba lodi si alafia ati ifẹ Ọlọrun. ninu ayọ wa, ki a ma a ranti ọrọ orin wa ti a nkọ bayi pe,

Kristien ma fiti wa isimi
Larin ọta lo wa
Gbọ bi Angẹli re ti nwi
Ma a ṣora



EVANGELIST AKANDE

* * *

Ki a maṣe yọ ayọ ti o le mu wa ṣibu s'ọwọ ọta wa, ki a si ma a ṣora ki a maṣe yọ ayọ ti a o fi huwa lodi si ofin ati ifẹ Ọlọrun wa, nitorina ni a fi nkilọ fun wa ninu Orin Dafidi ori 2 ẹsẹ 11, bayi pe, "Ẹ fi ibẹru sin Oluwa, ẹ si ma a yọ ti ẹnyin ti iwariri."

Ki gbogbo enia yago fun [illegible] ati ijọgbọn lorisirisi [illegible], nitoripe Ẹniti a nṣe odun Ọjọ'bi Rẹ lakoko yi ni Kristi, ẹniti a sọ nipa Rẹ ninu Isaiah 9: 6, bayi pe, "Nitori a bi Ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa, ijọba yio si wa li ejika Rẹ, a o si ma a pe orukọ Rẹ ni Iyanu, Oludamọran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, ỌMỌ-ALADE ALAFIA". Ẹni ALAFIA ni Jesu Kristi ti nṣe ọdun Ọjọ'bi Rẹ lakoko yi, ẹ jẹki a kun fun alafia ati ifẹ inu rere larin ara wa. Ki Ọlọrun Alafia ki o wa pẹlu gbogbo wa, Amin.






## ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

### Lati Ọwọ E. Alabi Thompson

"A O [illegible] orukọ rẹ ni Emmanuell itumọ eyi ti iṣe Ọlọrun wa pẹlu wa.

1. Ayọ kun ọkan wa loni
   A bi Ọmọ Oba
   Ọpọ awọn ogun ọrun
   Nṣe ibi rẹ loni
   E yọ, Ọlọrun d'enia
   O wa joko l'aiye
   Orukọ wo l'o dun to 'yi
   Immanuell

2. A wolẹ n'ibujẹ ẹran
   N'iyanu l'a jọsin
   Ibukun kan ko ta 'yi yọ
   K'o s'ayọ bi eyi
   E yo Ọlọrun etc.

3. Imọlẹ lati'nu Imọlẹ
   Tan 'mọlẹ s'okun wa
   K'a le ma fi isin mimọ
   Ṣe ranti ọjọ Rẹ
   E yo Ọlọrun etc.

### ITAN ORIN NA

Ifẹ ti Ọlọrun ni si araiye pọ to bẹ gee. O fi Ọmọ bibi Rẹ kanṣoṣo fun wa lati wa ṣe etutu fun ẹṣẹ. Eleyi fun wa ni idaniloju wipe, Ọlọrun Baba, ati ti Ọmọ ati ti Ẹmi Mimọ wa nigbagbogbo lati tọ wa si ọna iye ti olododo rin. Idaniloju yi ni ti ẹniti o kọ orin yi ti o si fi han wa ninu orin oke yi. Imanuell—Ọlọrun wa pẹlu wa.

# E KU EWU ODUN KERESIMESI

*(Lati oju we keje)*

lagbara ju iwa ibi, nitorina ni okunkun ko ṣe le bori imọlẹ. Ihinrere nla ni eyi fun wa. O si yẹ ka juba Ọlọrun layọlayọ nitori rẹ

Ọlọrun fi ifẹ rẹ han nipa riran ọmọ Rẹ wa si aiye. Ẹniti a bi ni awọ ẹda. O jẹ Ọlọrọ ṣugbọn nitori wa a sọ o di talaka, o bọ ogo Rẹ silẹ O si wa si aiye.

Ọmọ Alade Alafia ni Jesu O wa fun aiye ni alafia ati ifẹ inu rere, kini eyi jẹ fun wa gẹgẹ bi ẹni kọọkan ati gẹgebi orilẹ ede Enia Dudu (Nigeria).

Ohun meji pataki ni mo fẹ tọka si. Ekini ni pe Jesu ọmọ Ọlọrun le gba wa la kuro ninu awọn ẹṣẹ ti o mba igbesi aiye wa jẹ lọkunrin ati lobirin lọmode ati lagba. Lọna keji O le sọ gbogbo wa di okan ki o ma ṣe si iyapa larin awọn ẹya (Hausa, Ibo ati Yoruba. Ohun ti a ngbadura fun nisisiyi ni eyi. Lẹhin eyi Jesu le sọ gbogbo orilẹ ede di okan, ibajẹ Enia Dudu ati Enia funfun ati bẹẹ lọ.

Ẹ jẹ ki ọmọ Alade Alafia wọ inu okan wa, ki ifẹ-inu-rere si jẹ ti oni-kaluku wa.

Ẹni-Ọwọ Alufa A. S. Solarin, MBẸ, ti Ijọ Olowogbowo Methodist, Eko.

* * * *

E KU Odun, ẹ ku iyedun ọjọ ibi Kristi fun Ọdun yi a mu ire ati alafia fun gbogbo wa ati ifẹ inu rere si gbogbo enia jakejado aiye.

Ag. Supt. J O OKUNSANYA
U.A.M. Church (Ẹlẹja)
Oke Arin, Lagos.

* * * *

## Ohun ti Keresimesi jẹ si awa Musulumi

OLOTU, jọwọ gba mi laye diẹ 'nu iwe nyin oloyinmọmọ, lati ki gbogbo ẹbi ati ọrẹ ti nwọn jẹ onigbagbọ Kristi Jesu, Ẹniti awa Musulumi mọ oruko rẹ si Annabi Issa (Alaehi Salam) pe nwnọ ku ipalẹmọ Ọdun "Keremesi" ki Allah jẹki ọdun na yabo fun gbogbo wa jakejado aiye (amin). Ati lati sọ ohun ti Keresimesi jẹ si awa Musulumi.

...A gbọ pe, ọjọ-ibi Jesu Kristi ni awọn Kristiani ma a nṣe ni ọjọ kẹđogbọn oṣu kejila odun, lọdọọdun. Awa Imale ko ni igbagbo si pe ọjọ na ni nwọn bi I; nitoripe ohun ti o jọ bẹ ẹ kosi ninu Tira iwe ẹsin wa kankan rara (iwe ẹsin awa Musulumi). Bi o ba je pe mimọ wa nipa ọjọ ibi Jesu ni, a ba ri ẹri rẹ ninu iwe ẹsin wa laisi ani-ani, gẹgẹbi a ti ri ẹri ọjọ ibi Annabi wa (Muhammadu Salalahu alaehi wasalama) ti ṣe wa ninu awọn iwe ẹsin wa bi "Nuru Absari" pe ọjọ kejila ti oṣu "Rabiul-Awal" ni ọjọ -ibi Anabi wa na.

Awa Musulumi ko ni ifẹ si ọna ti nwọn fi nṣe Ọdun Keresimesi gba to bẹẹ rara: nitori iwa jagidijagan ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alalikali ati Kaoboi ma a nhu lasiko na; ati rakẹti yinyin ti o jasi ifowoṣofo ati ipalara. Ọlọrun sọ ninu Bibeli pe o di igbati enia ba fi iṣore fun awọn talaka kun iṣẹ Esin ni On Ọlọrun to le ni inudidun si ẹsin rẹ. Opọlọpọ ọkẹ aimoye owo ati dukia ni o ma nṣofo lọdọdun nipa rakẹti yinyin lọdun Keresimesi. Iru inawo wọnyi le di ohun fifi gba itẹlorun Ọlọrun nipa kikaṣa iṣe awa Imale ninu



Alufa Bọlaji Akewukewe

* * *

Ọdun wa gbogbo nipa fi fi iru awọn owo bẹẹ se ọpọlọpọ onjẹ ọdun ir uikoṣe bayi yio mu ki Ọdun na dara pupọ si loju awọn enia.

Mo fi ayọ okan gidigidi ki gbogbo ẹyin Kristiani taratara. Ọdun ayabo. Ki ominira ayọ ti mbọwa ṣe oju ẹmi gbogbo wa (amin).

Emi ni tinyin,
Alfa Bọlaji Akewukewe

---

MO ki gbogbo ẹnyin onkawe "Irohin Yoruba" ati gbogbo ọmọ enia jakejado aiye yi, ẹ ku Ọdun Keresimesi, ẹ ku iyedun. Ọdun yi jẹ pataki: nitoripe Ọọjọibi Ana Yisa (Jesus Christ) ni. Anabi na si ṣe ọpọlọpọ iṣẹ ire si aiye lasẹko tirẹ, apẹẹrẹ lati sin Ọlọrun dada ati lati ma a ṣe iṣe rara larin awa ẹda ti o fi silẹ ni ọpọlọpọ awa araiye ti a jẹ olufọkansin ntẹle.

Oluwa jẹki a ṣe ọpọlọpọ rẹ pẹlu owo, alafia ati idunnu o.

T. S. FUJAH,
Oloye Arẹ Eko.

## Isin ọjọ keresimesi

**CATHEDRAL CHURCH OF CHRIST**: 10 a.m. Bishop of Lagos.
**ST. JUDE'S ANGLICAN Church EB**: 9 a.m. The Vicar.
**JEHOVAH SHALOM**: 9 a.m. Bishop of Lagos. **Christ Church Eb.** 9 a.m. Rev. J. M. Lala. **St. James Sango** 9 a.m. Rev. H. O. Nelson Cole. **St. Peter's** 9 a.m. Rev. J. A. Ewetumo. **St. John's** 9 a.m. Bro. J. S. Oloyede.
**TINUBU METHODIST Church Circuit: Tinubu**: 10 a.m. English Rev. I. O. Oluwole. **Kroo**: 8.30 a.m. Bro. Potey Togo 5 p.m. Bro. Lawson.
**AGO IJAIYE METHODIST Church Circuit**: 10 a.m. Rev. T. A. Akinnigbagbe. **Apapa Elemu**: 10 a.m. Bro. Dr. **Mushin** 10 a.m. Bro D. F. Ekundare Fanlyesin. **Apapa Aiyetoro** 10 a.m. Bro. Ekekiri. **Bornu Crescent** 10 a.m. Bro. O. A. Fagbohun.
**ST. PAUL'S ANGLICAN Church Idi-Oro**: Xmas Eve: 10 p.m. Service of Nine Lessons. Rev. E. Ola Oyebajo. **Xmas Day**: 10 a.m. Holly Communion. Rev. E. Ola Oyebajo, 4 p.m. Holy Baptism Rev. E. Ola Oyebajo.

* *



Maria ati Ọmọ titun wa ni ibujẹ ẹran


Etu Funfun Omo owo

ASHTON & PARSONS

Wa fun ilera Omo re



Ti Ọmọ rẹ ba nke — Fun u ni Etu Funfun Ashton & Parsons — Yio si ba ṣerin





Etu Funfun Omo owo

ASHTON & PARSONS dara fun gbogbo idamu ehin omode

